## ỌRỌ ASỌYE NIPA IDIBO SI IJỌBA IPINLẸ IJẸSA

(Lati ọwọ J Ade. Tuton)

(Bẹrẹ lati oju iwe ọsẹ to kọja)

Njẹ ko ha tọ tabi yẹ lati ri wipe gbogbo Ijẹsa jẹ ilu Omiran kuro ninu ajaga orukọ Ẹgbẹ Alakuko tabi Ọlọpẹ ki wọn ma jẹ Ẹgbẹ Ọmọ Ijẹsa-Obokun? Nis-siyi ti o jẹ wipe Ọmọ-Obokun lo yan awọn to wọle si Igbimọ Iṣeto Ijọba Ijẹsa titun yi, ko ha yẹ ki awọn Aṣoju tabi Oludamọran (Kansẹlọ) na ti gbogbo wa yan, ti o si ṣe wipe gbogbo ẹniti owa ninu Ẹgbẹ ati ẹniti ko wa ninu ẹgbẹ ni wọn ma jẹ aṣoju fun, ki awọn enia na Aṣoju wa, jẹ enia ominira kuro ninu eto ati ajaga ati ijadu aṣẹ kaṣẹ ẹgbẹ kankan, ki wọn wa gẹgẹbi awọn Ọba ti wa, ati awọn Ijoye gbogbo ti wa, ti wọn ni lati ma joko pọ ṣe ipade lori gbogbo enia ninu ilu ati agbegbe Ijẹsa?

Mo nfẹ idahun si ibere yi pẹlu:. Njẹ ibi ha kọ ni ẹgbẹ mejeji wọnyi mu wọ inu ilu gbogbo nipa sisọ ẹgbọn di ọta aburo, iya di ọta baba, ọrẹ di ọta aladugbo rẹ, ilu si ilu, Ọba si Ọba ati ti iwa ika ati ireje nṣe be ninu ilu, ti ifọn jijẹ ati dulumọ npọ si lojojumọ, ti awọn ti o nipo giga Mẹmba ni tabi Minista ni ti aye won ko tẹ wọn lọrun, sibẹ ti wọn nṣọfa lori talaka ati mẹkunnu ti won npete ẹru owo wuwo le won lori lori-sirisi ọna abuja gbogbo? Mo a/ẹ alaye enikeni?

Njẹ bi awa enia ti nyọ moka le awon Asiwaju mejeji Azikuwe ati Awolọwọ, njẹ awọn enia na ha aronu nipa ọta ti ẹgbẹ-selu ki wọn si wa ol(n ninu awọn ilu wa alaimoye nipa eto iẹgbẹ - selu won si wa ofin ati aye tabi ona si ilodisi eto Ọlọrun le kuro arin wa? Gbogbọ iwa aifẹni, iṣọtẹ Iba-orukọ ọmọ ẹnikeji ẹni-jẹ ati iorisirisi ti mo ti ka soke Iwe yi o njẹ ilodi si eto ati ilana Ọlọrun.

Ti gbogbo wa ba mọ daju wipe ifẹgbẹmeji ṣe eto ilu yi nmu awọn ibi ti a ti ka sẹhin wọnyi wa, njẹ ko ha yẹ ki a kọ iṣẹ eṣu silẹ ki a pada si eto ifẹ afohuuṣọ. kanu fun ọmọnikeji-ẹni ati iwa ere gbogbo ti a ti nṣe lati ẹhin wa siwaju eto ẹgbẹ mejeji wọnyi, ki a si wa ni ominira Ọmọ-Ijẹsa Obokun? Ki o wa jẹ wipe awọn ọmọ Ijẹsa Obokun ti awọn ọmọ Ijẹsa Obokun yan ni wọn nṣe eto ati abojuto iṣẹ iṣelu Ijesha Obokun fun awọn ọmọ Ijẹsa Obokun?

Ti a ba gba iwọnyi ro ti awọn Baba wa, Ọwa ati gbogbo Balẹ, Lojaloja ati gbogbo Ijoye ba fi ohun, sọkan pa iaṣẹ fun awọn aṣoju wa lati wa ni ohun kan ati ede kan bi awon ti wa ti wọn ko ni eto ati aṣẹ si ati ṣe ẹgbẹ kọkan ninu Ẹnisi-ẹnisi (NCNC) tabi Afenifẹre (Action Group) dajudaju ilu Ijẹsa yio wa ni ominira dera ati alafia ninu ilana tii Jesu ati Ọlọrun pelu Obokun, ẹgbẹ kẹgbẹ yio kanṣẹ ninu igboro wa nipa ilana ati eto Ijọba ti ip nlẹ Ijẹsa-Obokun. Mo ṣe awọn ọrọ wọnyi ni idalọ wuruwu ni, ṣugbọn ni ọjọ iwaju a o ma mu ni die diẹ bi ẹyin ọkawe irawọ Obokun yi ba ti nfun mi ni esi asoye ati amoran si lori awọn ọrọ wọnyi. Mo duro nihin-Ọrọ ku-siwaju.



ARABIRIN FADAHUNSI

On ni iyawo Ọlọla J. O. Fadahunsi on jẹ ọkan ninu awọn aṣoju Obirin ni Ilesa. On ni pelu awọn to tẹle Gomina ti Ekun Iwọ orun de ile ẹkọ giga ti awọn obirin ni ọjọ Jimọ to kọja. awọn ọmọ ile ẹkọ giga na ṣere idaraya fun won.

## AKIYESI PATAKI

Ki ẹnikẹni ti o ba fẹ ra iwe Irawọ Obokun ni Ileṣa ma wa si Office IJESA PRESS No B 110 OKEṢA, Ẹ o ri ra nibẹ nigbakugba ti ẹ ba nfẹ.

ALABOJUTO

# Irawo Obokun fe irohin lati agbegbe Ijesa.



ẸGBẸ IRANLỌWỌ GBAJUMỌ CLUB

Awọn ẹgbẹ kan ninu awọn ẹgbẹ ti ọṣe pataki ni ilu Ileṣa Ọgbẹni George Ọṣọbu Ọmọle jẹ ọkan ninu wọn. Ọpọlọpọ awọn ọmọ ẹgbẹ na lo pesẹ sibiti Ọṣọbu ti ṣe iṣọmọ lorukọ ni ọsẹ yi lati ba yọ ayọ ọmọ titun na.

## IDAHUN SI ỌRỌ ỌGBẸNI J O OLUWAFẸMI

(Lati ọwọ J. O Ayiegbọ ẸsaOke)

Nipa ọrọ ti J. O, Oluwafẹmi sọ yi odun mọ mi pupọ mo se akiyesi ohuu ti awọn ijọba nse larin Igboro ilu kọkan, iranlọwọ ti awọn se lori iiti aii lo ri awọn gada omi' ati lori awọn ohun bẹbẹ ti emi ko le sọ, to si yẹ wipe gbogbo ẹnyin enia mọ awọn ohnn ti awọn ijọba nse iranlọwọ fun lori iiẹ aiye lati mu ki ilaju lewa lori ilẹ aiye tabi ki orilẹ ede le tẹ siwaju.

Sugbọn awọn ijọba ko fi ti awọn ojiṣẹ Ọlọrun si nu ero wọn tabi bi isẹ Ọlọrun yio ti se le tẹ siwaju gegẹbi ẹnikọkan ti se fẹ ki on tẹ siwaju ẹnyin ijọba kini ẹ ti ro ti Ọlọrun to da wa si? o ha yẹ wipe kosi bi tonfẹ abojuto ninu isẹ Ọlọrun bi? ibi to nfẹ abojuto wa ninu isẹ Ọlọrun gẹgẹbi J. O. Oluwafẹmi ti so sinu ọrọ rẹ ti Irawọ Obokun ojọ keje 7-3-55.

O sọ wipe awọn alufa wa larin ijọ Ọlọrun ti wọn yẹ lati ma san owo wọn tabi awọn ijọ miran ti wọn kolagbara lati kọ ile Ọlọaun tabi ti wọn kole san owo onisẹ to wa larin wọn.

Ọpọ awọn ile Isin lo ti wo pa/ ti ko si iralọwọ fun wọn ki se pe ẹyin ijọba ko mọ ohun toyẹ lati fise iranlowọ fun isẹ Ọlọrun? o ha jẹ pe awọn ijọ Ọlọrun ko le se ohun kohun fun yin bi? bi o ti lejẹ wipe awọn enia ko le se ohun kan fun yin ẹ ko ranti ọrọ Ọlọrun to sọ bayi pe bi ẹba fi ago omi fun awọn iransẹ mi ẹ ko se lasan, ọpọ enia ni anse lore ti o si nsan ore na fun pada melo melo ni ti Ọlọrun ẹjọwọ ẹyin ijọba ẹ bo juto isẹ Ọlọrun lorilẹ ede aiye ẹ dide iranlọwọ fun isẹ Ọlọrun.

Ọlọrun yio bayin di ijọba mu o Amin mo dupẹ pupọ lọwọ Olotu irawọ Obokun fun aye to gba mi Obokun agbe yino

## SISI ILE IKAWE TI OKE-BODE

Ọjọ kẹfa osu yi jẹ Ọjọ ayọ fun ara Okebode Lokunrin Lobirin Lọmọde ati agba, nitoripe iọjọ na ni wọn si ile ikawe wọn

Wọn bẹrẹ sisi ile na ni dede agogo mẹwa Owurọ, pẹlu orin ati adura lati ẹnu Ẹni Ọwọ J.Awodeyi.

Ogunlọgọ enia lo wa si ibi sisi ile ikawe na. Ero pọ tobẹ gẹ ti gbogbo iwaju ile na fi kun fun ero ti ko gba ẹsẹ, lẹhin pari orin ati adura tan ni Oloye Agunlejika II, lọja Oke-Bode si ilẹkun ano-wọle, na pẹlu owo ribiribi.

Lẹhin rẹ ni Oloye Risa na tun si iẹkun keji pẹlu owo bakana, bẹni awọn Ijoye ti o ku bẹrẹ sisi awọd ilẹkun ti o ku, bakana ni awọn enia pataki yataki ti o wa si ibẹ bẹrẹ si iṣi awọn leresi ti o wa nibẹ.

Lẹhin ti wọn wọle tau, ti gbogbo enia joko, awọn ti o wa ni ito na duro pẹlu ifarabalẹ Oloye Agunlejika II, Lọja wa ba wọn ṣọrọ.

Ohun kini ti o sọ nibe ki gbogbo wa Okebode ati agbegbe rẹ dupẹ lọwọ Kabiyesi Ọba AjimỌkọ II, Ọwa Ileṣe, ati Ijọba Ibile Ijeṣa fu iranlọwọ Owo nla ti wọn ṣe lati kọ ile na O mu anfani na lo lati tun dupẹ lọwọ Ajẹlẹ ti o lọ Ọgbẹni C. E Ales, o tun sọrọ iwunilori nipa Ologbe Dan Babatunde Risa Okebobe fun iranlọwọ ti ṣe ni asiko ti wọn nse wahala ki kọ ile na.

Lẹhin na lo gba gbogbo awọn tọ wa nibẹ nl-anju nipa ẹkọ, bi o ti ṣe jẹ pe ẹkọ jẹ ohun pataki ni akoko yi ati pe ilu tabi orilẹ ede ti o ba rẹhin nipa ẹkọ kole ṣe ohun kan ti o ba oju mu rara Diẹ ninu awọn pataki to wa si bi aṣeyẹ na ni awọn Ọgbeni James Lọmọla, A. O Agpamọ, J.B Olowolagba, Gabrael Asubiojo, Gabrael Esugbayi, M. A Adegbayibi, M A Alọ, M O Agbamọ, A A Adegbayibi, Ademọyọ, L U Edeme, J A Arimọrọ ati awọn bẹbẹ ti a ko le darukọ tan.

## IWE ALAGBAFO ASO

A ṢE IWE YI FUN ANFANI AWỌN ALAGBAFỌ ATI AWỌ TI A NFỌ ASỌ FUN. NIPA IWE YI AṢỌ KO SỌNU MỌ, RA RA ARIYANJIYAN KO SI MỌ NIPA AṢỌ.

TETE RA TIRẸ KI O TO TAN. IBA DIẸ NI A ṢE.

Ẹ O RI IWE YI RA NI OFFICE:-

IJESHA PRESS LTD. B110 OKESHA
P. O. BOX 23, ILESHA.

IYE OWO RẸ:-
ỌKAN:- 2/-

Lati mejila si oke:- 20/- fun dọsin

## AKIYESI

FUN GBOGBO OMỌ ẸGBẸ ACTION GROUP ỌPẸ

A fẹ ki gbogbo ọmọ ẹgbẹ Action Group mọ pe ipade ọjọ-mẹjọ-mẹjọ ti a nṣe ni Wednesday ko yi pada nitorina ki gbogbo ọmọ ẹgbẹ fi sọkan lati ma wa gbogbo ipade dede.

AKỌWE



J. O. OGUNṢEITAN

On ni Baba Ẹgbẹ Afẹnifẹre ti ilẹ Ijesa ogunlọgọ awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ lo wọle fun ipo Kansẹlọ ni ilu Ẹsa-Oke ati Ifewara ninu idibo ti asẹ laipẹ yi.

## Ikede Ati Ipolowo Oja Ninu

## "IRAWO OBKUN"

| | | | |
|---|---|---|---|
| | OJU EWE KINI | | |
| Igba | 1—12 | 8s. | fun insi kan. |
| Igba | 13—25 | 7s. 6s. | „ „ „ |
| Igba | 26—52 | 7s. | „ „ „ |
| | OJU EWE KEJI | | |
| Igba | 1—12 | 5s | fun insi kan |
| Igba | 13—25 | 4s. 6d. | „ „ „ |
| Igba | 26—52 | 4s. | „ „ „ |
| | OJU EWE KẸTA | | |
| Igba | 1—12 | 7s. 6d. | fun insi kan |
| Igba | 13—25 | 7s. | „ „ „ |
| Igba | 26—52 | 6s. 6d. | „ „ „ |
| | OJU EWE KẸJỌ | | |
| Igba | 1—12 | 6s. | fun insi kan |
| Igba | 13—25 | 5s. 6d | „ „ |
| Igba | 26—52 | 5s. | „ „ „ |

OJU EWE 4, 5, 6, Ti 7 JẸ OWO KANNA PẸLU TI OJU EWE KEJI.



OLOYE AGUNLEJIKA II LỌJA OKE BODE

On ni alaga nibiti ati si ile ikawe ti ijọba ibilẹ kọ si ilu rẹ laipẹ yi. On si fi owo to jọju si ilẹkun ile na.

## ỌLỌLA OLU KOMỌLAFẸ TAKO ATI ṢE IBUSỌ RELUWE FUN ỌPỌ ILU

(Lati ọwọ Ọpẹ)

Ninu ile igbimọ asofin nla ti Eko ni Ọgbẹni Oloye S. L Akintọla ti dalaba wipe oyẹ ki Ijọba se ona Reluwe lọ si awọn ilu pataki ti iya Reluwe nje gẹgẹ bi Ilẹṣa lọ si ọna ilu miran.

Bi oloye yi ti da aba yi ni ọlọla Olu Komọlafe ti nṣe asoju fun ilẹ Ijẹsa ba se tako fun ọrọ na pe ko si owo ni apo ijọba lakoko yi, jati le fi dawọ le irufe iṣẹ bayi ki Ijọba maba da igbese.

Ninu fifa ọrọ na mọ ara lọwọ Oloye Akintọla sọpe ifẹ gbogbo ọmọ Ijẹṣa ni lati ripe ọkọ Reluwe koja ni ilu wọn ṣugbọn ojẹ ohun ti o ya on lẹnu pe eniti ojẹ asoju fun ilẹ Ijẹṣa ni lati se atako ikan ti ibajẹ anfani ilu rẹ nitori ẹgbẹ oselu.

Awọn towa ninu ẹgbẹ alatako si sọfun awon towa lori aga ijọba pe itija ni fun wọn fun lilodi si aba rere ti ada, bayi ni aba na se sọnu patapata.

## GEORGE ỌṢỌBU ỌMỌLE ṢỌ ỌMỌ LORUKỌ

Laipẹ yi ni Ọlọrun ta Ọgbẹni O. George Ọṣọbu Ọmọle (7/6 a day) pẹlu Denikẹ iyawo rẹ lore ọmọkunrin lantilanti kan ni ile wọn ni adugbo Idifẹ.

Ni owurọ kutu ọjọ kerinla osu yi ni ọgunlọgọ awọn ẹgbọn, aburo ọrẹ, ana ati ojulumọ ti pese silẹ Ọgbẹni Ọsọbu yi fun ajọyọ siso ọmọ titun na ni orukọ.

Ki awọn enia tode ni Ọgbẹni Ọsọbu ti pese orisirisi onjẹ aladun ọtin pẹlu emu to sasa gba silẹ lati fise awọn towa nibẹ ni alejo.

Bi olukaluku ti njoko si aye ti ati pese silẹ ni angbe awọn onjẹ yi siwaju wọn onikaluku towa sibẹ ni o jẹ onjẹ ajẹti, nigbati odi dede agogo meji ọsan ni awọn Ẹgbẹ Iranlọwọ gbajumọ Club tise ẹgbẹ baba ọmọ yi desi ile rẹ lẹsẹkanna ni agbe awọn onjẹ ti ati pese silẹ siwaju wọn onikaluku wọn losi gbadun rẹ.

Bi awọn ẹgbẹ yi ti jẹun tan ni agbe ẹmu ile Alaji siwaju wọn ẹmu na si dara pupọ ju ọtin oyinbo lọ awọn ọmọ ẹgbẹ yi si tẹ ara wọn lọrun dada. Ogunlọgọ awọn enia ti o ba wọn ṣe aṣeyẹ yi siwa nibẹ titi di irọlẹ pẹlu ijẹ ati mimu. Asi sọ ọmọ na ni Olafisayọ.

Diẹ ninu awọn enia pataki-pataki ti owa sibi aṣeye na niyi. J. Adesami (alias Ọbaku) Olu George, Belo Obembe, Arowomọle, Abu Mechanic J. O. Awosan, Dọja, A. Owoẹyẹ, Ouni, J. Warnayọ E. Ọmọle, T. yerọ, ati ogunlọgọ ti ako le darukọ tan,

Akọle Olotu. Aki ọgbẹni George Ọmọle pẹlu iyawo rẹ Dẹnike ku orire ati ku inawo Ọlọrun yio da ọmọ na si pẹlu awọn ẹgbọn rẹ yio si tun pese ti anfani pẹlu. Iru ire bayi yio kan gbogbo wa o. amin

## ẸKUNDAYỌ OJO ṢE IFIRI IṢẸ KIKỌ RẸ

(Lati Ọwọ W. A. Fajinmi)

Ni ọjọ kẹrin 4-3-55 osu yi ni Ọgbẹni Ẹkundaayọ Ojo se ase ifiri (Freedom) iṣẹ ti o ti nkọ fun ọdun pupọ sẹhin, ni ọdọ ọgbẹni Adejuyigbe ni Odo ọja, O ṣe ase na ni adugbo Ifọfin.

Lati owurọ kutukutu ọjọ na ni ogunlọgọ awọn Ẹgbọn, aburo ọrẹ ati ojulumọ pẹlu awọn Ẹgbẹ atunkẹkẹ se (Cycle Re-pairer) ti pese silẹ fun olori wọn fun ti ajọyọ ifiri yi.

Ki awọn enia wọnyi to de ni ọgbẹni Ẹkundayọ ti pese orisirisi awọn onjẹ aladun, ọti (Beer) pẹlu ọtin oyinbo ati ọpọlọpọ ẹmu to gbadun lati fi se awọn to wa sibẹ ni alejo. Bi onikaluku ti njoko si aye rẹ ni a ngbe awọn onjẹ aladun na fun wọn.

Gbogbo awọn ti o wa si ibi ifiri yi ni o gbadun ara wọn pẹlu itẹ lọrun, ati onjẹ ajẹti, olukaluku wọn si bẹrẹ si gbadura fun ọgbẹni na pẹlu inu didun.

Ogunlọgọ awọn enia ti o wa ba wọn se aseyẹ yi si wa nibẹ di agogo mẹta ọsan. Diẹ ninu awọn enia pataki to wa sibi aseyẹ na niyi:- Adejuyigbe, Daniel owi D. Adewusi, M O Fayọriju, Bello Fatọba, George Ọshọbu (Alia 7/6 a day), Karimu Inuọlaji, Stephen Ajayi.

## OHUN IYALẸNU NI IPETU-IJESHA

(Lati ọwọ T A El-jofi

O jẹ ohun ti a ba enia lẹru ni ilu Ipetu Ijẹṣa ni ọjọ keji oṣu yi ni dede ago mejila ọsan ti kete ti awọn ọmọ ile-we wọle ti ọsan lati ri ọpọlọpọ awọn obi ọmọ wọnyi lati wa mu awọn ọmọ wọn.

Idi eyi nipe wọn gbọ pe ẹnikan ti de si ilu lati wa gun awọn ọmọ ile-we ni ABẸRẸ ORI awọn abalujẹ lo nsọ kiri.

Ko ku ju idamẹwa awọn ọmọ ilewe wọnyi si ilewe kọkan larin ilu yi: Awọn obi miran tilẹ nse pe le awọn olukọ lori bi wọn ko ba tete fun wọn laye lati mu ọmọ wọn jade lọ. Eyi ba emi papa lẹru bi ọkan ninu awọn olukọ wọnyi.

Abẹ awọn alabojuto lati bawa risi o.

## BADEJỌ ATI IYAWO RẸ SỌ AKOBI ỌMỌ LORUKỌ

Ni agogo marun gere owurọ ọjọ Jimọ 18-255 ni a bi ọmọbinrin kan fun Badejọ ni ile iwosan ti Wesley ni ọna Ijofi. Gẹgẹbi asa wa, wọn mura lati sọ ọmọ na lorukọ ni owurọ ọjọ kẹjọ. Nigbati o di owurọ ọjọ Jimọ 25-2-55 ni agogo mẹfa abọ gan a ni isin na bẹrẹ, Alufa Ẹniọwọ N. A Salakọ Alabojuto ijọ Eleto ni Ilesha ati agbegbe rẹ lo ṣe eto na gẹgẹ bi eto ijọ rẹ.

Diẹ ninu awọn orukọ ti a sọ ọmọ na ni Adesọla, Olufunmilọla, Ushenfowoke, Adetunji, Olubunmi Adedunkẹ, Abẹni, Ayọdele ati Ọmọyẹni.

Nigbati o di agogo marun irọlẹ ni wọn pe apejọ nla kan fun gbogbo awọn ọrẹ wọn ati awọn ẹniti o fẹ wọn fẹ ire. Ibẹ si kun akunyagba. Diẹ ninu awọn to wa ni awọn Iya afin, H. I. Ọsunloye, Hasstrup, Adedeji, Ọtẹgbayọ, Fadeyi, Fagbemiro, awọn arabinrin Abowaba,- Ọshundahunsi, Ojo, Sokunbi, Ikọtun, Fasọyiro, Longẹ, Opẹbiyi Adanri, ati awọn arakunrin Adeniyi Ọduntan, Lasebikan, Dada, Ayinde, Babatunde, Oyelami, Komọlafe Fadairo, ati gbogbo ọmọ ẹgbẹ ti a npe ni Ijẹbu Youths Welfare Union (Ẹgbẹ Ọdọ ti Ijebu) ati ọpọlọpọ enia ti a ko le darukọ.

Nwọn gbadura ẹmi gigun, ilera, agbara, ọla ati ọla fun ọmọ na ati awọn obi rẹ. Ire a mọri o.



ỌGBẸNI J. A. AKINYẸMI.

On ni ọga Ile Iwe giga ti Ilẹṣa On na jẹ ọkan ninu awọn ti o wọle fun ipo kanselọ ni iu ifẹwara laisi alatako rara.



LAWRENCE AMOKEODO

On jẹ ọkan ninu awọn ẹlufọkansin onigbagbọ ni ipinlẹ Ijẹṣa. O jẹ ọkan ninu awọn ogunagbɔngbo ninu ẹgbẹ iṣelu NCNC. O pẹlu awọn to nfi ọpọlọpọ akoko wọn kede ọrọ ẹgbẹ na ni agbegbe. Ọpọlọpọ igbimọ agbegbe ni ẹgbẹ na ti wọle laini alatako.

# AKIYESI PATAKI

A fẹki ẹnikẹni ti o ba fẹ fi irohin tabi ọrọ pataki sinu Iwe Irawọ Obokun ni Ileṣa tabi lati idalẹ fi irufẹ iwe bẹ ṣọwọ si Office No. B110, Okesha Street Ilesha.

**J. O. Awosan**
Alabojuto Olotu
B110 Okesha Street, Ilesha

## AKIYESI

A fi eyi kede fun gbogbo awọn aṣoju wa ti mba wa ta iwe irohin yi pe, aṣojuk'aṣoju ti ko ba san owo iwe tirẹ ki o to di ipari Ọsẹ kini ti yio tẹle Oṣu, a o da iwe rẹ duro lai si ifilọ tabi ifisun.

Nipa aṣẹ
Alabojuto

# AKIYESI

FUN GBOGBO ỌMỌ ẸGBẸ NCNC–ẸGBẸ AKUKỌ

A fẹ ki gbogbo ọmọ ẹgbẹ NCNC mọ pe ipade ọjọ–mẹjọ–mẹjọ ti a nṣe ni Wednesday ko yi pada, nitorina ki gbogbo ọmọ ẹgbẹ fi sọkan lati ma wa si gbogbo ipade dede.

# IṢẸ ỌLỌRUN LARIN IJỌ PETERU MIMỌ
(Lati ọwọ D T Ọsọmọ, Alufa Ijọ Isọna)

Iyipo-pada iṣẹ Ọlọrun mu emi ati awọn enia mi de si arin Ijọ yi ni ọjọ kọkandinlọgbọn oṣu December 1953, a si bẹrẹ iṣẹ ni ọjọ kini oṣu Januari ọdun yi. Ijọ tẹwọ gba wa t'ọwọ t'ẹsẹ

Bi o tilẹ ti jọ pe ọpọlọpọ ni awọn okan ti o yẹ ki Ijọ yi ti ṣe sẹhin ti nwọn ko ti ṣe, sibẹsibẹ a ri ami itẹsiwaju lọna pupọ. Ireti wa pe Ijọ yio ṣe daradara nipa iranlọwọ Ọlọrun.

Awọn isin ọjọjọ Isimi dara l'owu-Ṣugbọn ti alẹ ni ko ti tẹni lọ-ọrn to. A ma nni Isin ni Ede Gẹsi lẹkan l'oṣu, eyi si ndara Ilẹ-ẹkọ ọjọ isimi dara diẹ. Awọn agba diẹ ati awọn ọmọde diẹ lo nwa.

Awọn Ipade adura ati Klass la rin ọsẹ dara, a fi ipade ti awọn ti nkẹkọ fun Isami ni ko ti tẹni lọrun.

Ipade ẹgbẹ Aya Bisọbu nlọ dede lẹkan lọsẹ labẹ akoso Iyawo Alufa Mrs E A Osọmọ).

Awọn atunṣe pẹpẹpẹ ti a nṣe ninu ile isin Ọlọrun ati awọn hun ọsọ miran ti a se ninu ile Ọlọrun ọrẹ atinuwa ni a fi nṣe wọn. Tayọtayọ si ni awọn ti nwọn nse e si fi nṣe e. Ọlọrun ko si ni jẹ ki otan lọwọ wọn. Ki Ọlọrun si jẹ ki awọn ti nwọn ni iru ẹmi ilawọ fun iṣẹ Ọlọrun ba yi ma pọ si ninu ijọ yi.

Awọ oninu didun Ọlọrẹ na ni awọn:– A. F. Ọlalere, D. O Ogunniyi, Chief Lọmọdele. (Baba Ẹgbẹ Ijọ), Abigail Adeọla, Bernice Adebajọ (Ijẹbu), E. O Bọlarinwa, Dorcas Gboregun, Ẹgbẹ Alafia Obinrin, Ẹgbẹ Aya Bisọbu, Elizabeth Tinuola, Maria Iya Ẹgbẹ Ijọ, Eliza Faleye Ibironkẹ, Mary Adelẹyẹ Ologbe, Ester Famurewa, Dorcas Dada Iyalode, Rebecca Arẹ, Dorcas Aina Olọsi Mr. S. A Abe, E. Ojuọla, Ẹgbẹ Iwa Mimọ, Ẹgbẹ Ibukun Okelyin, Mr. R. O Thompson, E. O Ogunbiyi, Ẹgbẹ Afurugbin Ayeṣọ, Ẹgbẹ Ira Ọlọrun nian, Mary Adeọla Abigail Ajiyọ Mr M. O Fapohunda Maria Morẹnikẹ, Ẹgbẹ Irawọ Owurọ, Christianah Oluwarọmade, Felicia Bọsẹde, Felicia Ọnaọlapọ, Mr. M. O Adewọye, Janet Akinyanmi Mrs. C. A Lufadeju, Patiente, Lufadeju, Folaṣade, Chief D F Agbefidipẹ, Joseph Arẹ Balogun Ijọ.

A ki wọn ku inawo.

A sami fun bi ọgọrin enia lọ'ọmọde l'agba. Ọgbọn enia gba igbe ọwọ le lori ti Bisọbu (Confirmation) A fi ibukun sori Igbeyawo kan. Ọkunrin meji (ọkan ninu wọn Baba Ẹgbẹ ijọ, David Ajilore) ati obinrin kan sun ninu Oluwa.

Ijọ fi Oloye Lọmọdele Ojo joye Baba Ẹgbẹ Ijọ, Dorcas Gboregun jẹ ye iya Ẹgbẹ Bisọbu Dorcas Jọlade joye ọtun iya Ẹgbẹ ijọ David ati Abigail Adeọla joye Iyalode

Iṣẹ Ẹkọ wọn awọn ọmọde nlọ dede labẹ itọju awọn Ọga ile iwe wa mejeji awọn Ogbẹni M. O Ogunmokun, Bẹbaku ati awọn Oluko iyoku gbogbe. Iranlọwọ wọn ninu Iṣẹ Ijọ ko si kere. Ọgbẹn Omiyale gba Iwe Aṣẹ Bisọbu fun Ikawe Mimọ ninu ijọ Ọlọrun.

Ijọ ti dawọ-le ogiri mimọ yi ile Alufa ka, Nwọn si nṣe Aga Iwasu ọwọ. Ki Ọlọrun jẹ ki ijọ yi ma lagba siwaju ati siwaju ninu iṣẹ dere.

Ẹgbẹ akọrin nlọ Ijọ labẹ Aluduru ngbiyanju lati le mu Isin Ọlọrun dun lọjọjọ Isimi Ki Ọlọrun jẹki aiye wọn o toro.

Awa fi ọpẹ fun Oluwa nitoriti anu Rẹ duro lailai. Adupẹ lọwọ Igbimọ Ẹkun Ileṣa ti nwọn rohin Ijọ wa dara kun Ijọ Mẹriu miran ti nwọn fun ni oye PARIṢI.
ASEYI ṢAMỌDUN O.



ỌGBẸNI D. A. ARIYỌ.

O jẹ ẹnikan pataki ninu awọn ti o ni ile itawe pataki ni Ilesha ti a npe ni Burma Memorial Bookshop. Ile rẹ ni awọn ẹgbẹ ti a npe ni Igbogi Progressive Union ti se ipade pataki laipẹ yi.

